# EKO AKETE.

## IWE IROHIN OSOSE.

ỌRỌ IFOJUSUN:—
"Emi yio fi ohun ti o ndun Makunnu han awon Alagbara, Ngo si je Alagbawi awon Odi".—W. T. Stead.

Vol. II. No. 54. SATURDAY, JULY 21, 1923. Fourpence.


ỌGBẸNI OYINBO F. A. PICKLES

nṣe *Cinema* ni Opopo nla lẹmẹta lọsẹ. Awō-ṣẹju ni awọn aworan rẹ. Ina Manamana ti a si fi nṣe Ẹrọ na mọlẹ bi ọsangangan. Ọrẹ, lọ fi onjẹ oju f'oju nibẹ. Ẹmẹta lọsẹ lo nṣe e *Monday, Wednesday* ati *Saturday*, ni agogo mẹjọ abọ alẹ (*8.30 p.m.*)

**A. KESSLER,**

Ile owo Oyinbo German Hamburg

Iwọ le ranṣẹ Ẹrọ-Iranṣọ "*Mundlos*" ati "*Adler*" nibẹ bẹ si ni Ẹrọ-riran bata pẹlu.

Ẹ tọ Ọgbẹni A. Kessler lọ si 7 Labinjo Lane, kọrọ Williams Street.

CHIEF SECRETARY'S OFFICE 25 JUL 1923 LAGOS








A nranṣẹ orisirisi ọja fun enia to tete nlọ nilẹ ni *Nigeria*

Ọja tiwa ya. A si ni ọja wọnyi fun tita:—Ohun ẹrọ orin, Awo-Abọmafọ, Kẹkẹ-ologere t'Ọkunrin t'Obinrin, Waji.

Ẹ le ri Ẹrọ Iranṣọ "*Mundlos*" ra lọdọ J. S. Johnson, Alhaji Masu, ati lọdọ H. Campos ti Campbell Street.

**Mundlos on top Mundlos.**

**Mundlos on top Mundlos.**

LAGOS STEVEDORING COMPANY.

**ALL STEVEDORING WORK**
undertaken at lowest possible prices anywhere in the Lagos area.

**GOODS HANDLED CAREFULLY AND EXPEDITIOUSLY.**

Estimates given for the handling of goods under any circumstances.

*PRICES ON APPLICATION*
to

**S. I. M. Johnson,**
9, Scale Square,
Phone 227 Lagos,
P.O. Box 498.

---

QGBẸNI J. C. VAUGHAN.

Ti Ile-Qja Sheffield ni Ita Kakawa ati Ile-Qja "*Excelsior*" ni Ita Agarawu, ni omuruu awọn ohun sikole fun tita ni owo ọpọku-oyọku.

O ti nṣowo Irin Iṣẹ lorişirisi lati adọta ọdun sẹhin titi di oni.

ATARI AJANAKU ni QGBẸNI na jẹ ninu awọn onişowo Irin Iṣẹ ni ilu Nigeria.

QKQ tita wa ni owo pọ o.

---

QGBẸNI DURO THOMAS.
ONIŞOWO PATAKI.

Ti 55, ita Faji, l'Eko, ni orişirişi Qja to de fun u lati Ilu Germany fun tita: awọn nkan Awọ abọmafọ, Cement, Akara, ati ọpọlọpọ ọja miran.

Ẹ lọ de ibẹ, Igbo-Akan 'mọpa ni ohun to ni

Bi ẹ ba fẹ, ẹ kọwe si i, *Number* Apoti-Iwe rẹ ni Ile ipin iwe (*General Post Office*) ni 374. *Number* fifi-ẹrọ manamana ba a sọro (*Telephone*) ni 243.

---

Ẹ WA RA QPQ QJA.

Qgbẹni D. B. OŞUNTOLU, onişowo Qlanrewaju ni ọpọlọpọ ọja fun tita ni Şabu rẹ ni
No. 44 Balogun Street, l'Eko.

Ninu awọn ọja rẹ ni iwọnyi:– Ikoko taba, Carpets Panu ikole, Aşọ oniruru, Itẹko, Baranje, Olowonyọ, Yomini, (*Sattin*)

Ati orişirişi nkan atata miran, Oja Qgbẹni yi roju o si lere ninu, ọpọku-ọyọko ni.

Ẹ lọ ra ti nyin nibẹ.

---

WHAT IS MORE REFRESHING than a sound sleep on a comfortable Bed? or time-saving than a thoroughly good sewing-machine?

A large consignment of Brass Iron-Beds, Bedsteads, (new arrivals from Germany.) is just to hand at Mr. Duro. Thomas's establishment 55, Massey St., Lagos.

An early call at this address for your selections will well reward your labour.

Prices attractive and alluring.

CALL TO-DAY NOT TOMORROW.

---

KILO NGBE MI LQ YI O? ORUN!
AŞQ NYIN FAYA, Ẹ LQRAN.
AŞQ NYIN FAYA, Ẹ LQRAN.

IBUSUN-ILESANMI ati
MASINI-A-NJUWON

Qgbẹni DURO THOMAS.

Onişowo-towolawi, ni awọn IBUSUN mèrémèré ounde to şeşẹ de fun u lati ilu Jamani wa fun tita ni Ile Qja rẹ 55, Ita Mase leti ita Faji, l'Eko.

Ifà mbẹ fun awọn to ba tete lọ ra tiwọn nibẹ: owo yẹpẹrẹ ni a nta wọn, bẹni awọn Qja na si "ka 'yin" to.

E lọ ba Àwúre nyin pade nibẹ.

*Editor & Proprietor*:—
ADEOYE DENIGA,
*Office*: 24, Williams Street,
P.O. Box 286,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ.

| | Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/0 | 14/- |
| Oṣu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oṣu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor*.

## GBOHUN-GBOHUN.

:o:

BALOGUN DODO NDAWA;
A BẸRẸ F'OJI O!

Ki Iwe-irohin yi to jade Balogun Durojaiye Ṣowẹmimọ yio ti pada lọ si Ibadan; Balogun na de l'ẹnu ọsẹ to kọja fun ajọyọ Ọjọ Ibi ti a rohin rẹ ni lọlọ yi o si wọ sile Ọgbẹni M. O. Coker (Eman: S. Coker ni orukọ Ọgbẹni na ri, o si jẹ ọkan pataki ninu awọn ọmọ Ọgbẹni Isaac Asalu Coker ti Abẹokuta.)

Ẹnikẹni to ba ri jagun na pẹlu aṣọ wa (Aṣọ Yoruba) ti o nsaba ati ma wọ yio ṣebi Ọgbẹri kan lasan ni ṣugbọn. kan a na, Ọ mọ pe ọkunrin lo kan yẹn, nitoripe o jinlẹ ninu Iwe gidigidi; nigbati a lọ ki i ti o si nsọ nkan iwọn lile logoji ọdun fun ni gẹgẹbi o ti wa labẹ ẹkọ *Ven: Archdeacon* Henry Johnson ẹgbọn awọn *Ven: Archdeacon* N. Johnson Dr. O. Johnson Ologbe ati Mrs. Allen ni *C.M.S Grammar School* l'Eko lati 1878–1882 ti a si tun pe pada lẹhin ọdun diẹ ti o jade Ile-iwe lati wa ṣe Olukọni ni Ile Iwe kanna yi (1886) labẹ Ẹni Ọwọ I. Oluwọle ti o di *Bishop* nisinsinyi o si sọ pe ọga wọn "Henry J" (orukọ aladun yi ni wọn npe e nigbana) ki ifi ẹkọ to ba fun nwọn kọ ninu Iwe *Greek*, tabi *Latin* jafara; ẹnu ya ni lọpọlọpọ si gbogbo ọrọ yi.

Ọgbẹni yi si mọ Balẹ Ilu Ọgbẹni Henry Carr ni *School* nigbana ati awọn jakanjakan bi Ọgbẹni Herbert Macaulay Rev: S. A. Coker ati J. R. Ṣanu o si sọ pe on kọ Ologbe Ẹni Ọwọ J. S. Fanimọkun ni'we ri ni sa tirẹ, ọrọ pupọ lo sọ, o sọ nipati Ipalẹmọ ẹbun ti nwọn fẹ fun *Bishop* Oluwọle fun ẹyẹ ọgbọn ọdun ninu oye rẹ o si sọ pe on mura lati pari ede ko yede to wa larin awọn Bọkinni diẹ nibi nipati ọrọ yiyanni a ko yanni si Ajọ Igbimọ to mbọ, nipati Abẹokuta. Balogun na lọ si Ibadan gẹgẹ bi a ti wi ni *Wednesday* ọsẹ yi.

AGBAKO ORI EDE!

O ta si ni leti finrin pe Idagiri kan ṣẹlẹ lojiji ni *Lagos Street, Ebute Meta*, pe Aisan Aiperi kọlu ọmọkunrin kekere kan, Iya rẹ si nkigbe fun iranwọ, awọn aladugbo si kun ile ṣoṣọ tobẹ ti nwọn ti ilẹkun mọ awọn enia omiran l'ode bi nwọn ti nwa aṣọ ninu agbọn lati fi bọ ọmọ yi lara, ko ba le lagun a gbọ pe koko owo kan ti a ta bọ silẹ ṣugbọn a ko mọ ẹniti o mu owo na, a gbọ pe ponwun mẹwa (£10) ni nwọn fọn lọ patapata; bayi ni Iya ọmọ yi fi (£10) ra ẹmi ọmọ rẹ silẹ lọwọ aran buburu yi.

AJỌ KOTU O!

A ṣe Ipade kan ni Ile Afari ogun l'ẹhingbẹti ni *Saturday* t'o kọja, Ọgbẹni James George ni Alakoso rẹ, ọrọ ti nwọn sọ pataki ni pe ki irẹpọ wa larin awọn ara Ilu nipati ohun ribiribi t'o mbọ nipati yiyan enia mẹta si Ajọ Igbimọ Aṣofin ti Ijọba, ninu oṣu *Octobar* ọdun ni.

Diẹ ninu awọn t'o s'ọrọ l'eyi Ọgbẹni James George Alakoso, Ọgbẹni ọlọla S. H. Pearse, Adebẹsin Fọlarin, 'Sekitẹri; Ọgbẹni Ọlọla Eric O. Moore, Ọlọla Dr. Ọbasa, Dr. Da Rocha, awọn Ọgbẹni Wahabi Shitta, J. Alẹṣinlọyẹ Williams, E. Olu Bright, Braimah Ogongo ati *Editor* "Eko Akete.

### "EMI NKU LOJOJUMO"

Bayi ni ọrọ Paul Mimọ wa si iranti wa nigbati a gbọ iku Ọgbẹni Joseph Nathan John ti o ṣẹlẹ l'ọsẹ yi, akikanju ninu Isin Ọlọrun ni ologbe yi jẹ ni *Church* rẹ, Tinubu; a si gbọ pe o ti ṣaisan sara ri ki Ọlọjọ to de gbukẹ ni lọlọyi.

Ki Baba maṣai f' oriji i.

### EWU LO LORI RẸ EWU LỌ YE!

Ọran ko dun fun awọn Obinrin Ṣekiri ati *Calabar* ni alẹ *Saturday* to kọja nigbati awọn ọtẹlẹmuyẹn lọ ko wọn ni *Williams Street, Portonovo Market Street* ati ibomiran. B'o lọ o ya mi ni wọn mu koṣe-koro pẹlu awọn ti awọn mu ko niye. Eyi t' o ya ni lẹnu nibẹ ni pe ni *Monday* t' o kọja yi ti a gbe awọn apani-mayọda wọnyi duro niwaju Adajọ, gbogbo wọn ni a da silẹ.

### NIBO NI AGO NBỌ?

Ni oru *Sunday* t' o kọja idẹ omi nla kan (*Main Pipe*) fọ nitosi ile Ọgbẹni James White, irogiri omi yi ko fi aye orun silẹ fun ẹnikan ṣoṣo l' adugbo kun: ni wara ṣe ṣa omi nfẹ wọ 'le pẹtẹsi pẹlu Maṣalaṣi ọpẹlọpẹ Ọgbẹni T. I. Kester to pe awọn Panapana lati ki agbara omi na wọ bi iṣẹju.

### KABỌ ỌMỌ LIṢABI.

A ki Mrs. S. Ẹdun Cole aburo Dr. Oguntọla Ṣapara I. S. O. kabọ lati Ẹnugun. Iya afin na de ni *Wednesday* ọsẹ yi, Alafia kọ l'ẹ de? *Nna o!* (eyi ni kiki enia lede Ibo.)

### ALAKỌRI NṢOWO KO PE.

A yọ ọkunrin kan ti o ti jẹ Agbawo Oyinbo ri ni ṣe alakọri si lọ haya ile kan nibiti o gbe nko awọn awọluje obinrin si fun ôwô adanu pẹlu awọn ọkọnrin nipa bayi o ngba komiṣọn bi tọrọtọrọ (3d.) tabi sisi sisi (6d.) lori obinrin kọkan lọwọ awọn ọkọnrin to ba wa sibẹ, ṣugbọn ki alapa-maṣiṣẹ na to ma ba "iṣẹ" lọ titi ọwọ tẹ ẹ a si ba a ro 'jọ iyoku iregbe ẹwọn l'o nsọrọ nisinsinyi nibiti yio wa titi oṣu mẹta!!!

### KABỌ ỌMỌ ALARẸ.

Ọgbẹni A. O. Delo-Dosunmu bọ lati Ilẹ Ọba ninu ọsẹ yi o si ti di *Lawyer*.

### ABIAMỌ KU 'RỌJU.

A ba Ọgbẹni Oni ti Ita Akanni kẹdun iku ọmọ rẹ Dayọ-agbalagba-ọmọ—to ṣẹlẹ ninu ọsẹ yi, a gbọ pe ọmọ na ṣeṣi mu egbogi riri-orun-sun kọja ala lo mu ọlọjọ de ba a lapapa-ndodo.

———:o:———

Ajọdun ọdun ti *Bishop* I. Oluwọle, D.D. di ọgbọn ọdun ninu oye *Bishop* ri akekẹ ti nwọn ṣe fun iranti ọjọ na ni Abẹokuta, ni ọjọ kọkandinlọgbọn oṣu *June 1923* ni Ijọ Ake.

———

Nigbati o ti di agogo mẹjọ arọ ọjọ na gan ni agogo kinni fun Isin Onjẹ Alẹ Oluwa ti bẹrẹ si lu. Gbogbo awọn Alufa Olukọni, Katikist ati Aṣoju Ijọ ni gbogbo Igberiko ẹkun Abẹokuta ati ni Abẹokuta papa lo ti pe wabi sinu *Church* Ake.

Lẹhin Ipinfunni Onjẹ Alẹ Oluwa gbogbo awọn Ẹgbẹ kan ti a npe ni *Scout* ni ab itọju Ọga Ile-ẹkọ Giga *Grammar Schoo* Mr. W. R. B. Kuyẹ, yi gbogbo Ijọ ka bẹni gbogbo awọn Ile-iwe kekeke ti o w ninu Ijọ ti C.M.S. ṣe pẹlu, ranyin n gbogbo Ilu ndun—irohin ko to afojuba.

Nigbati agogo mẹrin abọ (4.30 p.m.) ọsar lu, isin agbajọ gbogbo Ijọ C.M.S. wa s Ijọ St. Peter Ake; gbogbo awọn Alufa Alufa Abẹokuta ati gbogbo agbegbe rẹ tun pesẹ ṣibaṣiba pẹlu.

Awọn alabojuto Ijọ kekeke miran [illegible] awọn Olukọni awọn ọmọde.

Ọba wa—*His Highnes the* Alake Ade mola II wa ni ipo rẹ gbagba.

ọn Alufa ti o pesẹ sibi Isin Akanṣe nwọnyi:—

No J. A. Lahanmi Alufa Ijọ Ikereku
J. J. Ransome-Kuti „ „ Ake
J. J. Olumide „ „ Igbore
S. A. Delumọ B.A. „ „ Igbein
E. S. Aiyebiwo Alufa Ijọ Ọfada, etc.
J. F. Peters „ „ Iṣaga, etc.
N. O. A. Morgan „ „ Iporo—Ake
E. O. L. Ṣorẹmẹkun ti Ijọ Ake
D. M. George
M. O. Akinọla Alufa Ijọ Oṣiẹlẹ, etc.
S. P. Adeyinka „ „ Ṣunrẹn etc.

Revd. J. J. Ransome-Kuti, Alufa Agba ti Ijọ Ake lo wasu lati inu ọrọ Ọlọrun—*I Cor: 15 10* Nipa Ore Ọfẹ Ọlọrun mo ri bi mo ti ri, etc.

O sọ fun ni ninu Iwasu rẹ, "O di ọdun mejileladọta t o ṣiṣẹ Ọlọrun gba, nigbati a ba ka gbogbo eyiti o fi ṣe iṣẹ Olukọni mọ; eyiti o di oleye *Bishop* ni o jẹ ọgbọn ọdun ni ọjọ kọkandilọgbọn oṣu *June 1923*. O sọ fun ni ninu Iwasu rẹ na ti inurere rẹ si gbogbo enia ninu gbogbo Ijọ ti o wa l'abẹ rẹ ati nibi gbogbo; O sọ ti suru rẹ, ti ibanikẹdun rẹ, ti ifọkanran iṣoro rẹ, ti agbara ti Ọlọrun fi jinki rẹ pe enia bi iru rẹ ṣọwọn.

O sọ fun ni pe Ọmọ-Ilu wa nihin ni on iṣe ni Itoko, Awoniga ni Baba rẹ on si mọ ẹdun ọkan wa, o si fẹran wa d'opin.

O sọ fun wa pe awọn Alufa ti o fi jẹ oyè jẹ mọkandilogọrun—99 *priests he did ordain;* awọn ti o fi ọwọ lelori fun *Confirmation* jẹ ẹgbamẹtala—2,600 *were confirmed by him during these thirty years.*

O sọ fun wa pe Ẹni-ọwọ J. A. Lahanmi ti o jẹ Olori gbogbo awọn Alufa ti o wa ni Abẹokuta jẹ ọkan ninu awọn eso iṣẹ rẹ ati ọpọlọpọ ninu awọn na ti o wa ninu isin na gẹgẹbi Alufa.

Lẹhin ti Alufa na pari Iwasu rẹ ni o bọ si ori duru, ti *Katikist* Ijọ Gbagura Mr. Ṣoyọde Ọtọlorin fi orin sẹnu ni ohun ilẹ wa pẹlu ẹgbe.

Gbogbo Ijọ ndun yungba, akọdele ni orin na jẹ fun olukuluku ẹniti o wa sinu Isin-akanṣe na.

Akanṣe orin na ni eyi:—

## ORIN ỌPẸ

Fun ọgbọn Ọdun ti
BISHOP I. OLUWỌLE, D.D.,
**1893—1923.**

1. Ẹ f' ọpẹ f' Oluwa (2)
Ẹnyin Onigbagbọ, fun Bisọpu Oluwọle.

2. Ọmọ Awoniga (2)
A yin Jesu sẹ, t' o fi ọ jẹ Iranṣẹ Olu.

3. Ọba t' o ni wa o (2)
On l' o yan ọ jẹ Bisọpu Oluwọle.

4. Olu t' o ra wa o, (2)
On l' o yan ọ jẹ Bisọpu lat' ọgbọn ọdun.

5. A dupẹ f' Ọlọrun (2)
Ẹnit' o lo ọ fun Iṣẹ Rẹ f' ọgbọn ọdun.

6. Ẹ f' ogo f' Ọlọrun,
Ẹnyin Onigbagbọ, fun Bisọpu Oluwọle.

7. Ogo fun Baba o (2)
Ẹnit' o yan ọ, Bisọpu Oluwọle

8. Ogo f Ọm' Ọlọrun (2)
Ẹnit' o yan ọ jẹ Bisọpu Olori Ijọ.

9. Ogo f' Ẹmi Mimọ (2)
Ẹnit' o ya ọ fi sọto s'olori Ijọ.

10. Ọmọ Awoniga (2)
Awa gbagbọ, awa mọ p' Olu l' o yan ọ.

11. Ọba Aiyeraiye (2)
Awa nyin Ọ fun Bisọpu Oluwọle.

12. Ẹni Mẹtalọkan (2)
Awa nsin Ọ Olodumare Ọba Aiyeraiye.
*Aṣẹ, Amin o, Bẹni ko ri o.*

FRANCUS.

# EKO AKETE.

Eko, Saturday, July 21, 1923.

## JẸJẸ MI NI NLỌ, PANṢAGA MA PA MI!!!

Ni ọjọ pipẹ, o jẹ aṣa awọn onilu wa nibi l ti ma lu ilu wọn pẹlu orin ti a fi s'oke iwe yi, nigbana Eko ko ti bajẹ to ti ode isin inyi, ẹnikẹni to bá si w'oye iṣẹ-alai lojuti ti pupọ ninu awọn obinrin Ṣẹkiri ati awọn obinrin *Calabar* nṣe larin wa ni Ilu yi, yio mọ pe lati igbati Ijoba koko ti da wa pọ mọ wọn ni ọjọ ekinni oṣu *May* 1906 ni akoko Gomina Egerton ni a ti ri esekoyi ana nipa yiya ti awọn obinrin wọnyi ya wa s'Eko bi eṣu, ti ọgọrọ wọn ko si ni iṣẹ meji ju iṣẹ ki nwọn ma ta ara wọn bi ẹja l'ori atẹ lọ; iwa yi bu-a ya tobẹ to fi lẹ pe ni iwọn ọdun to kọja nigbati awọn Ọlọpa dosiṭi ka nwọn, ti a si fi wọn sun ofin pe, nwọn mba ilu jẹ, nipa iwakiwa wọn lalai ni ọkọ kan gbọn, pọnwun marun-marun ni Adajọ bu fun ẹnikọkan ninu wọn; eyi si mu ki pupọ ninu wọn f'Eko silẹ; die si lọ wa ọkọ ni ṣugbọn, ki lo tun de? Lẹhin igbati nwọn sinmi iṣekuṣe yi, koi l'ọjọ koi l'oṣu, nwọn tun fọn si i; o tun di pe ki awọn Ọlọpa tun ra wọn mu ni ẹnu ọsẹ to kọja, a gbọ pe Ọgbẹni R. Rẹis ọkan ninu awọn olori Ọlọpa ilẹ yi A-hi-mimu-ole-lọtọ lo ṣ'ọdẹ ti ọwọ fi ba to iwọn mejidinladọta (48) ninu wọn ni alẹ *Saturday* to kọja; ṣugbọn nigbati a tun fi wọn sun nkọ, kilari? A gbọ pe Adajọ (ki ṣe Adajọ to da ẹjọ ti akọko leyi) ni ẹri ti awọn Ọlọpa mu wa lati fi ba awọn masendoki obinrin na ro'jọ, ko tẹ on l'ọrun; a sọ pe Adajọ ni awọn Ọlọpa ni lati mu awọn to nḍmọ f'ile haya fun awọn obinrin bẹ fun ṣiṣe irufẹ iṣẹ bayi wa siwaju on, nigbana ni on yio to kọngọ fun wọn pẹ idi la so Ifa mọ, Ọpẹlẹ ni ngbọrun ati pe nitoriti awọn Ọlọpa ko ṣe eyi, o da gbogbo wọn silẹ ni *Monday* ọsẹ yi; ọrọ ti a sọ pe Adajọ sọ na le jẹ aymike kan ninu ofin (*Technical Point in Law*) ṣugbọn ni tiwa a ro pe o ku diẹ ko to, nitoripe ko ẹnikẹni ti ko mọ pe iṣẹ agbere r pupọ ninu awọn obinrin na nfi jẹun o Awa papa ri diẹ ninu wọn ni Isal *Williams Street* nigbakan ni'le ti nwọn haya, ti awọn ọkọnrin si ngba yin lọdọ wọn; a si fẹ sọ pe ko si ọkan ninu awọn obinrin wọnyi ti yio gbo'ju gba'ya sọ fun onile pe "O jare" aibamọ, panṣaga ni mo fẹ ma ṣe ni Ile na o! ti onile na jẹ gba fun u.

Nitorina a kesi awọn Alaṣẹ ilu ki nwọn ma ṣai wa ọna miran ti nwọn yio fi din ibajẹ Agbere ti awọn Obinrin yi nṣe lojukoju yi ku, bi bẹ kọ, ki ẹnu ma ṣe ya wa ti awọn ẹlomiran ni ilu ekere ba sọ ilẹ yi l'oruko pe Eko jẹ ilu agbere.

A fẹ ki awọn Baba ilu, awọn Ọgbẹni J. Egerton Shyngle, O. Alakija, ati G. D. Agbebi, ba wa f'oju agba bẹ ọran yi wo. Ẹnyin la fi ṣ' agba, Ẹnyin la fi ṣe. Ẹ gba Eko lọwọ awọn obinrin a-ko-tiẹ-wa-ba-ni-yi. Panṣaga a-biyakọ bẹ rẹ!!!

---

Lagos, Nigeria,
20th July, 1923.

The Editor, "Eko Akete."

Dear Mr. Editor,

Permit me through the medium of your invaluable paper to call the attention of 'Keswick' Convention to the sad omission of special meetings for Boys in the Programme for this year. The foot note in the posters informs the public that Boys and Girls will not be admitted to the evening meetings. In lieu of this special meetings were arranged for Girls, but no such priviledge was extended to Boys

Far am I from suggesting any manifest disregard for the spiritual welfare of Boys and from regarding the omission as being in any way punitive; but I think attention should be emphatically drawn to this serious *omission* to prevent its recurrence and to enable all—men and women, boys and girls—equally to reap abundant spiritual blessings from the Conventions.

Arrangement for a Boys' Meeting to be held on Sunday afternoon is strongly but respectfully recommended.

Thanking you, Mr. Editor, for space allowed.

I remain,
Yours sincerely,
PEDAGOGUE.

Editor—"Eko Akete."

Mo ba ọ yọ papa fun ti pe Iwe Irohin rẹ di ọmọ ọdun kan ninu ọsẹ ti o koja. O yẹ ki a ki ọ ku ewu nitoripe o ko de Ile Ẹjọ bo yala o jare ni o, tabi o si tun jare na ni o, o ko bu Ọba, o ko bu ijoye talaka ko si sun o gba Lọya apapadodo, fi ọpẹ fun Ọlọrun. Ẹnikan a ma kọrin pe "Ati ẹbi ati are, ori mi ma jẹki nri ẹjọ!" Mo tanma pe bi mo ti nsọrọ yi mo nṣe ẹnu fun ogunlọ'ọ awọn ti o gbadun Iwe Irohin rẹ, ni ọjọjọ *Saturday* ni a si ma nwọna fun ijade "Eko Akete" bi igbati Siṇẹma (*Cinema*) tabi *Magic Lantern* nyọ oniruru aworan jade wa, ati talaka ati ọlọrọ, kọ si ẹniti ko gbadun ọkan ko jọ kan ihin ti a ngbọ ninu "Eko Akete" lọsọsẹ eyiti a ki ba ti gbọ rara bi o ṣo pe Iwe Irohin rẹ ko si, Sara rẹ re o!

Awọn miran ti nwọn ri wa tan a ma sọ nipa awa enia dudu pe, ko si ohun ti a le ṣe ni aṣepẹ, ibẹrẹ a ma dara ṣugbọn a ki le gbe e jari, aṣiri na ko ju eyi lọ pe "ki o wo, ki o wo" ni orin wa si ara wa, kaka ki a gbe ara wa ni igbọnwọ soke pe ki nkan kekere le di nla, ẹja! bi a ko ba le bẹ ẹwọ na kuro, a o fa a tipatipa ti ọwọ na ki yio fi ṣe 'lo mọ lailai, a ma gbagbe pe "Awo ni 'gbe awo nigbọnwọ, agidi malaja, awo ni Ile Ifẹ, bi awo ko ba gbe awo nigbọnwọ awo a tẹ." to to o! Ki Ọlọrun jare ki o ma bukun awọn ti ngbe ọ nigbọnwọ soke, kiṣe nipa kiki owo nikan, ṣugbọn nipa imọran ododo ti o le ṣe enia ni rere; maṣe fi iru awọn enia bẹ silẹ. Mo ki ọ fun ayan rẹ, ati aiṣarẹ rẹ, pelu iwa ọyaya ti o fi ngbe iṣẹ na l'ẹsẹ, ati ẹmi iforiti ti i mu ki iṣẹ yọri si rere. Ajinde yio ma jẹ fun ọ!

A nireti pe ohun rere ni akọtun ni ao ma ri ninu [illegible] Irohin ti o bẹrẹ ọdun keji rẹ yi, tobẹ ti yio fi [illegible] o ma fa enia mọra lati ra ati lati ka a. Ki [illegible] run rẹ le jẹki o ma fi ilera ṣe iṣẹ rẹ na nso, [illegible] ẹ nigbati iṣẹ ba bowo tan, ki Ibi Itẹwe tabi [illegible] ibo igbalẹ Iwe Irohin rẹ (*Offices*) le tobi, pẹlu [illegible] pọ akọwe, ani ki o tilẹ ni ẹrọ Itẹwe ni ikawọ ara rẹ.

A yin Ọlọrun logo fun eyiti o jẹki o le ṣe yi, yio si tun ran ọ lọwọ lati tun ṣe ju bẹlọ, tobẹ ti a ko ni ma juwe Iwe Irohin to mu oruko rẹ lọwọ bi Iwe ijọsi, (iwe ti o ti ku fin fin,) ṣugbọn ki iyi rẹ le tubọ ma ga siwaju.

Iwọ Iwe Irohin "Eko Akete," Editor sọ pe o bẹrẹ ọdun keji, ọmọ oṣu mejila ko gbọdọ ma ma gbiyanju lati ra, maṣe yarọ o, ma si 'ṣe kanju lati rin, ki o tun ru diẹ si i ninu ohun rere gbogbo ni ọdun keji yi o, bi o ti yọri sode yi, maṣe moka rara mọ o, ki a si ma 'gbara' rẹ losọsẹ bi ti atẹhinwa. Ẹnyin janmą gbogbo ẹ ma ṣatilẹhin fun ọrẹ wa yi, Ọgbẹni Adeoye Deniga duduyẹmi ọkunrin, a fi Ibaka ṣana ki Edunmare jẹki o le ma mu ilu eko wa yi dun bayi lọ titi. Deniga ọrẹ agba, maṣe fi ofin ọba ṣire o, maṣe fi ọdọ agba sile, maṣe fi ọmọ enia ṣire, inu kan ni ko o ma sa li ogun, yio ṣe ṣe o Ẹ ba mi ke fatiha gbogbo Janma.

ABDUL-AZIZI.

---

## NGO TẸ Ọ NI JIGÁ, ṢAURA.!!!

Awọn Imale yio kirun ni Atalata *Tuesday 24th July 1923* nwọn a si se àsè ni ọjọ keji *25th July 1923* gẹgẹbi *Nigerian Moslem Almanack, 1341* ti awọn A. A. Ipayẹ & Bros ti fi kọ wa. Iwe *Almanack* ti Ọdun titun ną nbẹ fun tita lọdọ Saka Jojo *Victoria Road* ati Jinadu Mati ni Isalẹgangan ati lọdọ awọn A. A. Ipaiyẹ & Bros ni Isalẹgangan ṣile kan pere ni.

---

## IWE ITAN T'O KẸ RIRI

Ọrẹ,

Lọ ra Iwe Itan ti Ibadan ati ti Ọyọ ni Ile-itawe ti *C.M.S.* nibi, ṣile meji meji ati sisisisi ni a nta ọkọkan.

Ọgbẹni Isaac Akiyẹle l'o ṣe Iwe Itan ti Ibadan Ẹ o si ri ọwọ rẹ ninu ti Ọyọ pẹlu.

---

## BOOKS! BOOKS!! BOOKS!!!

"History of Ibadan" and "History of Ọyọ" by ISAAC AKIYẸLE are on Sale at the C.M.S. Bookshop, Lagos, 2/- 6d. each.

---

## AWỌN IWE ỌGBẸNI J. G. KUYẸ

Fun Ile Ẹkọ.

| | | |
|---|---|---|
| A. B. D. ALAWORAN | ... | 3d. |
| IWE ALAWORAN KINI | ... | 7d. |
| IWE ALAWORAN KEJI | ... | 9d. |

Awọn iwe wọnyi ko ti si lode ni sā kan nitori ogun Germani, ṣugbọn wọn tun de nisisiyi, a si le ri wọn ra ni Ile Iwe tita ti C.M.S. ninu ilu yi tabi lẹhin odi.

Itan ati owe ti o wa ninu iwe wọnyi dara pupọ, bẹ gẹgẹ ni awokọ inu wọn dara fun ọmọde to, ẹniti o ba dan a wo yio ri pe ọgbọn ẹniti o ti jẹ olukọ awọn ọmọde fun ọdun pupọ li a fi to awọn iwe na lẹsẹsẹ, kiṣe iṣẹ *ṣare nbaja*.

A le ri awọn iwe wọnyi ra pẹlu lọdọ oniwe ni ẹdin owo, 66, Ibadan Street, Ebute Mẹta.

IGBẸ L' OWO WÀ.

LAGOS—EKURO.

Bi awọn oyinbo ile-òwò wọnyi ti gba Ọja (*Produce*) l' ọsẹ yi ni eyi.

Ẹgbẹ Odo-Ọya (Niger Co.)
G. B. Ollivant,
Oyinbo Agbẹra (Lagos Stores)
MacIver, African
Association, John Holt, Miller Bros.
Cooperative Wholesale Society Ltd.,
Jurgens Colonial Product.
£11 10—£12 fun *ton* kan.

EPO.

£22 10—£23 ni gbogbo awọn Ẹgbẹ oyinbo ti a darukọ wọnyi gba *ton* kan.

COCOA.

£18 10—£22 10 fun *ton* kan bakanna.

KANO—COMPETITIVE PRICES

Ground Nut—
Skins 1/11½ per lb, Hides 4½ per lb

## POSI T'O JIRE.

Ẹnikẹni le ri awọn Posi alarabara ti a ti ṣe lọsọ lati Ilu Ọba wa ra ni ile ọja Kọlade ni 40A Joseph Street, Okepopo, ati ni No. 1, Moloney Bridge St., Anikantamọ. Ọtọtọ ni iye owo wọn, lati £6. 6. titti de 25 guineas. Aṣọ oku (*Shroud*) Yọmini to funfun bi lekeleke si wa nibẹ fun tita pẹlu.

Ẹ lọ ri tabi ki ẹ kọ'we si:—

Ọgbẹni HUDSON COLE,
P.O. Box 477,
Eko.

## MR. A. KESSLER,

7, LABINJỌ LANE, WILLIAMS STREET, LAGOS.

# Pilsener Beer! Pilsener Beer!!

*One's thirst is quenched on taking a glassful*

"LION BREWERY BRAND"

**Reduced to 32/- per case.**

*A TRIAL, FRIEND.*

Ọgbẹni na ni Ọti *Beer* tò yo-lù-wá ni tita ṣile mejilelọgbọn pere ni fun Apoti kọkan.
Igbadun mbẹ nibẹ ẹ jare. Ẹ rẹ tọ wò.

*Telegraphic Address* :—**BANK ANTHONY**

TOKUNBO, LAGOS.

Telephone No. L230, G.P.O. Box No. 300.

*Residence and Office 137 Tokunbo Street Lagos.*

Ọgbẹni A. BANK ANTHONY AND SONS jẹ Onişowo to nranşẹ ọja fun tita lati ilu ọba (*England*) wa O si ma nfi ọja şọwọ sibẹ na pẹlu.

Diẹ ninu ọja ti o ma nra ni ilẹ yi ti o si ma nranşẹ ni wọnyi :—
Gẹdu, Rubber, Cocoa, Ekurọ, Epo, Obi, Igi Osun, Agbado, Iwo Malu, Awọ orişirişi.

Diẹ ninu awọn ọja ti o ma nranşẹ fun lati Ilu Ọba (*England*) wa fun tita ni ilu wa ni wọnyi. Aşọ orişirişi, Akara Oyinbo, Ẹran oniyọ ati ọpọlọpọ nkan miran bi iru eyi ti o ta ni ilu wa ati Posi isinku iru eyi ti awọn oşişẹ wa ko le şe ni ilẹ wa.

Wo aworan ọkan yi, wa si ri daju pe awọn oşişẹ ilẹ wa ko le şe iru rẹ.



Irohin ko to afojuba lọ si ile rẹ ni No. 137 Tokunbọ Street wa si ri daju pe ki işẹ asọdun o ni ti talaka o si ni ti Olowo eyiti a fi igi şe tabi eyiti o jẹ onidẹ (Brass)

Ẹ kọwe tabi ki ẹ ja waya si i a o si fi Posi ranşẹ si nyin nibikibi ninu *Motor Tran-port.*

## Preachers for To-morrow.

AWỌN ONIWASU ỌLA.

ROMAN CATHOLIC (HOLY CROSS)

Masses will be sung by Priests appointed.
Awọn Paddi ti a yan yi o ṣe Isin ni gbogbo akoko wọnyi.

(MORNING)

Masses Isin Arọ.

6.30 7.30 8.30 9.30
7.30 8.30 9.30 10.30.

(EVENING.)

Masses (Benediction) Isin Ibukun.

4.45—5.30 6.45—7.30.

ST. MICHAEL'S (Lafiaji.)

MORNING. 7 a.m.—8 a.m. 8.30 a.m.—9.30 a.m.
EVENNING. 5.45—6.30 p.m.

ANGLICAN

| Time. | | Preacher. |
|---|---|---|
| 9 a.m. | Christ Church | The Vicar |
| 6.30 p.m. | do. | do. |
| 9 a.m. | St. Paul's (Breadfruit) | Ven. Archdeacon T. A. J. Ogunbiyi |
| 6.30 p.m. | | do. |
| 9 a.m. | St. John's (Aroloya) | Rev. H. V. E. Johnson |
| 6.30 p.m. | do | do |
| 9 a.m. 6.30 p.m. | St. Peter's (Alapako) | Rev. J. A. Cole |
| 9 a.m. & 6.30 p.m. | Holy Trinity (Ebute Ero.) | Rev. S. J. Gansalio |
| 9 a.m. | St. David's (Jordan) | Rev J. A. Leigh |
| 6.30 p.m. | | do. |

WESLEYAN

| | | |
|---|---|---|
| 10.30 a.m. | Tinubu | Rev. D. A. Bababunmi |
| 7 p.m. | do. | Rev. A. N. Cole |
| 10.30 a.m. | Ereko | Rev. J. Allen Angus |
| 7 p.m. | do.* | Rev. E. K. Ajai-Ajagbe |
| 10.30 a.m. | Olowogbowo | do. do. |
| 7 p.m. | | Rev. S. A. Pearse |
| 10.30 a.m. | Ọbun Eko | do. |
| 7 p.m. | | Bro. E. E. Ajọṣẹ |

AFRICAN (COMMUNION)

| | | |
|---|---|---|
| 9 a.m. | Jehuvah Shalom | Bro. W. K. Fafunwa |
| 7 p.m. | do. | Rev. J. F. Ogunko |
| 9 a.m. | Erelu | „ M. B. Newton |
| 7 p.m. | do. | Bro. J. H. Lawson |
| 9 a.m. | Bethel | Rev. J. A. Wright |
| 6.30 p.m. | | Bro. A. Abọyade Cole |
| 9 a.m. | Zion | „ A. Olugbile |
| 6.30 p.m. | do. | Rev. N. J. D. Ṣomuji |
| 10.30 a.m. | African Methodist | Bro. J. A. Oshodi |
| 4.30 p.m. | | „ Samuel Johnson |

FIRST BAPTIST CHURCH

| | | |
|---|---|---|
| 10.30 a.m. | | Bro. J. O. John |
| 5.30 p.m. | | Rev. J. R. Williams |
| 9 a.m. | Ararọmi (Baptist) | Bro. J. Tubi |
| 4 p.m. | | „ Joseph Bandele |

EBENEZER (BAPTIST)

| | |
|---|---|
| a.m. | Bro. J. F. Oshodi |
| 30 p.m. | „ Joseph Adekọya |

BROTHERHOOD

7.30 a.m. Ilupesi Pastor. A. Adedeji Iṣọla
7 p.m. do.

ST. STEPHEN'S (EPETEDO)

9 a.m. & 4 p.m. Very Rev. J. G. Campbell

AHMADIA (ISLAM)

6 a.m. Fajir Service Y. P. O. Ṣodẹyinde
5.30 p.m. Open Air Service Imam K. R. Ajọṣẹ (Bamgboṣe Street.)

COLONIAL CHURCH. (ODAN)

8 a.m.—Holy Communion

6.45 p.m.—Evensong and Sermon; Rev. H. A. Lewis

SALVATION ARMY.

Services at Glover Memorial Hall, 10 a.m. and in the Streets.

CHURCH OF GOD

10 a.m. 22 Ọdunlami Street, Breaking Bread
7.30 p.m. Campbell Street Open Air Service John P. A. Taylor, Wm. C. T. Terrell

---

MESSRS. J. R. THOMAS & SONS of Lisabi Hotel, Itori, beg to inform the public in general that they have been licensed by the Nigerian Railway to sell and serve refreshments etc etc, to all passengers travelling on trains on up and down journey at Itori, Aro and Olokemeji Stations at very moderate prices This venture has already been opened by them to the public at the aforesaid Stations any one travelling up to Ibadan and back and needing supply of any kind of refreshment should intimate us through the Station Masters Iddo to Ibandan, and *vice versa*.

## N. V. Handlemattschappij V.H.

J. F. SICK ati AWỌN ẸGBẸ.

No. 7, Ita Ibode laiku, Feti *Glover Memorial Hall,* (*Customs Street,*) EKO.





Awọn Oyinbo Onişowo yi nranşẹ MASINI-ARANSO ti a npe ni VESTA Nos. 1-4 t' ọlọwọ ati t' ẹlẹsẹ ni owo to rọju a le fi iyẹ-owo wọn han ẹnikẹni to ba lọ si Ile-owo yi.

Nwọn mura tan lati şe adehun pataki pẹlu ẹnikẹni to ba fẹ ranşẹ Mejila tabi jubẹ lọ ninu MAŞINI na.


---


"EKO AKETE."

A le ri Iwe-Irohin yi ra lọdọ Aşoju wa.

Ajenifuja Stores, 109 Broad Street, LAGOS.

Ọgbẹni VIDAL R. COLE.



## Sorinolu's Grammar School.

*The first ever Established in Abeokuta and Ijebu-Ode since 17 years ago.*)

All Grammar School Lesson efficiently taught to Advantage and Success.

*Tuition Fess Rated by the Readers:—*

Primers I and II—3/- *per Quarter.*

Readers I to III—3/- *per Quarter.*

Readers IV and V—6/- *per Quarter.*

Classes I to III—9/- *per Quater.*

Boarding Fee—£1 2s 6d, Monthly.

This is beside the Tuition Fee; and includes. Lodging, Cloth-Washing, and Cooking Services

PLEASE NOTE!

Payments strictly in advance; otherwise the Pupil shall suffer a temporary cessation from School and Boarding.

For futher particulars apply to

ARIYỌ ŞORINOLU,
Iporo Ake, Abẹokuta. *Principal & Proprietor.*

---

## *The Philharmonic Band.*



Awọn oni fere yi nfun pẹtẹ, ilù nwọn si dun bi oyin l' eti.

Owo ti a nfi pe nwọn ko pọ, nwọn ko si kọ lati lọ si ilu ki ilu.

Ẹni ba fẹ wọn, ko kọ iwe si

*THE SECRETARY,*
c/o Anfani Motors
The Marina Lagos.

## ALASE LEATHER FACTORY.
### "ILE ALAWỌ."

Awọ ẹsẹ bata (*sole-leather*) ti a ṣe daradara, ti o lẹ ti o si pupa yo. ati Awọ Hausa ni orisirisi awọ, yala ni pupa, funfun, dudu, ofẹfẹ, ati orisi awọ miran ni a nta ni ọpọku ọyọku.




Bi o ba fẹ wa wo Ile Awọ nla yi, ti iru rẹ ko si ni *Nigeria*, bi bẹkọ kọwe ṣọwọ pẹlu owosi :—

E. B. BEYIOKU-ALASẸ
108, Moloney Bridge St.
P. O. Box 368, Lagos, Nigeria.
*Telegrams*. —Alawọbata, Eko.

### NOTICE.

When replying advertisers, please mention "Eko Akete"

### AKIYESI.

Ti ẹ ba fẹ lọ si ọdọ awọn ti o polowo ọja sinu iwe-irohin yi, ẹ jare ẹ sọ pe ninu iwe-irohin Eko Akete ni ẹ ti ri ipolowo ọja na ka.

## JACOB A. AJAYI,
### *General Woollen Trader,*

has on hand Woollens in endless variety at 50, Dosunmu Street, Lagos, at

***Prices to suit everybody.***

*Call now, fortune awaits you.*

CHIEF SECRETARY'S OFFICE
26 JUL 1923

### ỌGBẸNI BEN. Ọ. JOSEPH

Ti Ile owo G. B. Ollivant ni Ẹhin Ọgba (*Victoria Road*) tun bẹrẹ si ta ọti lorisirisi, o si fi eyi sọ fun awọn onibara rẹ lailai ati titun pe aye mbẹ fun wọn lati ma wa ba on ra ọja na lowo-lọwọ ni ẹhin Ọgba. (*Victoria Road*)

## DRESS-MAKING.

### "KỌ-OGE-NIWẸ" SEWING INSTITUTE,

119, Tokunbọ Street, Lagos.

If you want a perfect fit and artistically made dress, patronize the above institute and you will be amply satisfied.

Girls requiring tuition in the modern and up to date style of Dress-making please apply to the above Institute.

*TERMS MODERATE.*

---

### "KỌ-OGE-NIWẸ" SEWING INSTITUTE,

119, Tokunbọ Street, Lagos.

Mrs. Frances Adeyemi Thorpe (Nee Green) K'ogeniwẹ, a fi iṣẹ ni lapa ṣe fuja, bẹrẹ si Iṣẹ Ọna rẹ ni No. 119 Tokunbọ Street. Ni ti aṣọ ritan ni aṣa orisirisi ko ni ẹgbẹ.

Ẹyin ọmọge ti nfẹ iṣẹ kọ, Ẹ lọ ri i.

Printed at "Tika-Tore" Printing Works, 20, Market Street, Lagos, and Published by Adeoye Deniga at 24, Williams Street, Lagos, Writer and Lecturer.